**ONDO JOURNAL OF ARTS**
**Faculty of Arts**
**Adeyemi Federal University of Education, Ondo**
OPEN ACCESS https://ojaafued.com/index.php/ojall *Volume 1, Number 1, 2025*

# Ìlò Àwàdà fún Yíyanjú Ìṣòro Ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ Ajẹmọ́dìílé Gẹ́gẹ́ Bíí Ó Ṣe hàn Nínú Àwọn Àṣàyàn Ìwé Eré-Onítàn Yorùbá

**Olúfadékẹ́mi Adágbádá**
olufadekemiadagbada@gmail.com
**Department of Linguistics and Nigerian Languages**
**Olabisi Onabanjo University, Ago-Iwoye**
**&**
**Grace Olúwákẹ́mi Adéfowópè**
kemiadefowope@gmail.com
**Our Lady of Apostles Secondary School (Private), Ijebu-Ode**

***Àṣamọ̀***
*Ohun tí ó bí iṣẹ́ ìwádìí yìí ni àwọn ìṣòro tí ó ń kojú ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ nínú ètò ìdílé àti ipa tí àwọn ìṣòro wọ̀nyí ní lórí àwùjọ. Lára àwọn ìṣòro wọ̀nyí ni ìfojútẹ́ńbẹ́lú-ẹni, ìfẹ̀mí-òkùnkùn báni jà, àìnímọ̀ọ̀tótó, ìjà, ìmẹ́lẹ́, àìnítẹ̀ríba, àìlẹ́kọ̀ọ́-ilé àti àṣìlò ọmọ-ọ̀dọ̀. Èròńgbà iṣẹ́ ìwádìí yìí ni láti wò bí ìlò àwàdà ṣe lè yanjú ìṣòro ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ajẹmọ́dìílé nípa ìfòótọ́-ọ̀rọ̀ gún aṣebi lára nípasẹ̀ ẹ̀rín rírín, kí ó lè jẹ́ àríkọ́gbọ́n fún ẹlòmíràn. Ọgbọ́n ìwádìí tí iṣẹ́ yìí tọ̀ ni ṣíṣe ìtúpalẹ̀ kíkún lórí àkóónú àṣàyàn ìwé eré-onítàn méjì, ìyẹn Ìyá Yáádì tí Dòsùmú kọ àti Nítorí Owó tí Ìṣọ̀lá kọ láti wo bí àwọn òǹkọ̀wé ṣe lo àwàdà fún yíyanjú àwọn ìṣòro ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ajẹmọ́dìílé. Tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀-wò-lítíréṣọ̀ ni ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ tí iṣẹ́ yìí rọ̀ mọ́ nítorí pé láti inú àwùjọ ni ìlò àwàdà ti máa ń jẹ yọ. Iṣẹ́ ìwádìí yìí rí pé lára okùnfà ìṣòro ìbára ẹni-gbé-pọ̀ ajẹmọ́dìílé ni àìnífẹ̀ẹ́, àìnísùúrù, àìkọ́mọ-lẹ́kọ̀ọ́-ilé tó àti àìníṣẹ́. Iṣẹ́ ìwádìí yìí gbà pé ìlò àwàdà kó ipa ribiribi nínú yíyanjú ìṣòro ajẹmọ́dìílé dé àyè kan gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àwọn ìwé àmúlò. Ọ̀nà àbáyọ tí Iṣẹ́ ìwádìí yìí dábàá ni pé kí àwùjọ fi àyè gba ìlò àwàdà gẹ́gẹ́ bíi ìjánu fún ìwà ìbàjẹ́, kí ẹ̀mí ìkóra-ẹni-níjàánu lè fẹsẹ̀ múlẹ̀ síi nínú ìdílé, kí àwọn tí pẹ̀tẹ̀pẹ́tẹ̀ àwàdà bá sì ta sí lára gbìyànjú láti ṣe àtúnṣe.*

**Kókó-ọ̀rọ̀:** Àwàdà, Ìbára-ẹni-gbé-pọ̀, Ìkóra-ẹni-níjàánu, Ìṣòro, Ìdílé

## 1. Ìfáárà

Adẹ́rìn-ín pòṣónú ni àwùjọ mọ aláwàdà sí (Comedian). Àwàdà máa ń jẹ́ dídáni lára yá àti pípani lẹ́rìn-ín. Àwàdà ṣíṣe máa ń jẹ́ kí ẹrù wúwo tí ó kó àyà ẹni sókè wálẹ̀, tí ìtura yóò sì dé bá ọkàn ẹni fún sáà kan. Àwàdà gbígbọ́ máa ń mú ẹ̀rín àrín tàkìtì wá, a sì máa jẹ́ kí ènìyàn gbàgbé ìnira tí ó ń báni fínra fún sáà kan. Apàrònúrẹ́ ni aláwàdà jẹ́ láwùjọ ẹ̀dá adáríhurun. Kò sí ibi tí

àwàdà ṣíṣe kò ti lè wáyé; láàrin mọ̀lébí, ibi iṣẹ́ òòjọ́, ilé ìjọsìn, ibi àpèjẹ, ilé ijó, ilé ọtí, agbo òṣèlú, agbo òṣèré, láàrin irọ̀-sí-irọ̀, ọkọ sí aya, aya sí ọkọ, ìyàwó sí ẹbí ọkọ, ẹbí ọkọ sí ìyàwó, ẹ̀gbọ́n sí àbúrò, ìyakọ jíjẹ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èròǹgbà àwàdà ni láti pani lẹ́rìn-ín, kí ó sì dáni-lára-yá (entertainment), síbẹ̀, ìṣojú-abẹ-níkòó máa ń jẹ yọ nínú rẹ̀, tí èyí sì lè fa kí irú ẹni tí ó bá ta bá ṣe àtúnṣe.

**2. Tiọ́rì Ìṣàmúlò**

**2.1 Tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-Ẹni-Gbé-Pọ̀-Áwùjọ-Wo Lítíréṣọ̀**

Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2014: 36-37) jẹ́ kí a mọ̀ pé ohun tí a pè ní “Soṣiọ́lọ́jì Lítíréṣọ̀” jẹ́ ọ̀rọ̀ tí onímọ̀ èrò ìjìnlẹ̀ kan tí a ń pè ni Hippolyte Taine; ọmọ ilẹ̀ Faransé rọ fúnra rẹ̀ láàrin ọdún 1828 sí 1893. Ó ní ète láti sọ àgbéyẹ̀wò iṣẹ́ ọnà dàbí ti ìmọ̀ sáyẹ́nsì ló fa ìṣẹ̀dá Soṣíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀, tí ó sì jẹ́ ìmọ̀ tuntun ní agboolé ẹ̀kó nípa iṣẹ́ ọnà. Tíọ́rì Soṣiọ́lọ́jì Lítíréṣọ̀ jẹ́ abala ìmọ̀ méjì tí ó papọ̀, soṣiọ́lọ́jì àti lítíréṣọ̀. Tí a bá fẹ́ wádìí ìjìnlẹ̀ nípa àwùjọ àti ẹ̀dá inú rẹ̀, soṣiọ́lọ́jì àti lítíréṣọ̀ ni a lè pè láti wá yanjú irú ìṣòro tí a bá dojú kọ. Ìdí nìyí tí Hoggart nínú Adéyẹmí (2006:8-29) fi jẹ́rìí sí i pé “Without the full literary witness, the student of society will be blind to the fullness of a society” (Láìsí ẹ̀rí kíkún láti ipasẹ̀ iṣẹ́ lítíréṣọ̀, akẹ́kọ̀ọ́ nípa àwùjọ kò lè rí ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ). Ohun ti èyí túmọ̀ sí ni pé ìmọ̀ lítíréṣọ̀ àwùjọ kan ṣe pàtàkì, bí a bá fẹ́ ní ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ nípa irú àwùjọ bẹ́ẹ̀. Pẹ̀lú àkíyèsí yìí, a lè sọ pé soṣiọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ ni ẹ̀kọ́ ìmọ̀ nípa ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin lítíréṣọ̀ àti àwùjọ. Sàlámì (2019:151-153) náà fara mọ́ ohun tí àwọn onímọ̀ ń sọ pé lítíréṣọ̀ kò wà lásán, a kò sì lè ya lítíréṣọ̀ àti àwùjọ tí ó bí i. Ọ̀nkọ̀wé gan-an fúnra rẹ̀ kò já bọ́ láti ọ̀run, inú àwùjọ ló ti wá, gbogbo ohun tí ó bá ń ṣẹlẹ̀ sí àwùjọ, òun náà nípìn-ín níbẹ̀. Gbogbo ìrírí àwùjọ kò sẹ̀yìn rẹ̀, pàápàá èyí tó jẹ mọ́ ètò ìbára-ẹni-gbé-pọ̀; ètò ìdílé, ètò ìṣẹ̀lú, ọrọ̀-ajé, ẹ̀sìn, ètò ààbò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Síwájú síi, inú àwùjọ ni òǹkọ̀wé ti ní ìmọ̀ tí ó gbá jọ, ìrírí rẹ̀, ìrònú rẹ̀ àti ibi ti ìmọ̀ rẹ̀ fẹ̀ dé. Nítorí náà, soṣiọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ ni ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin òǹkọ̀wé, àwùjọ àti iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bí ààrò mẹ́ta ti kì í da ọbẹ̀ nù. Iṣẹ́ ìwádìí yìí gbà pé má-yà-mí ni ọ̀rọ̀ lítíréṣọ̀, òǹkọ̀wé àti àwùjọ jẹ́. Ẹ̀rí tí ó dájú ni pé gbogbo iṣẹ́ òǹkọ̀wé alátinúdá ló ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwùjọ tí a kọ wọ́n fún, yálà eré-onítàn, ìtàn-àròsọ tàbí ewì. Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé inú àwùjọ ni ìlò àwàdà ti máa ń jẹ yọ, ìdí nìyí tí iṣẹ́ ìwádìí yìí fi gùn lé tíọ́rì yìí gẹ́gẹ́ bí òdiwọ̀n fún àtúpalẹ̀ rẹ̀.

**3.1 Aáyan àwọn Ọ̀mọ̀ràn Ìṣáájú nípa Àwàdà**

Lára àwọn onímọ̀ tí ó fún àwàdà ní oríkì ni Meredith, Trypanis nínú Adélékè (2020:118-138), Mordi (2020:112-117), Adégbìtẹ́, (2019: 23), Bámidélé (2001:2), Aristotle nínú Heath (2009:3) àti Bergson (1981:328-332, 2003:24). Meredith tí Adéléke (2020:128) ṣàmúlò sọ pé "Àwàdà ni gbígbé ọ̀rọ̀ kalẹ̀ ní ọ̀nà tí yóó gbà jọni lójú, tí yóò sì ṣe orísun ìrànlọ́wọ́ fún ẹ̀rín". Ó tẹ̀ síwájú pé ẹ̀rín yìí ni orísun ìrànlọ́wọ́ fún ìlera pípé àti pé àwàdà ṣíṣe fi hàn pé ẹni tí ó bá ń rín ẹ̀rín kì í ṣàárẹ̀, ojú rẹ̀ yóò sì máa rẹwà sí i ni lójoojúmọ́ bó bá ṣe ń jí. Aristotle tí Heath (2009:3) ṣàmúlò ki àwàdà pé:

> Comedy is one of the oldest forms of drama. It highlights that human beings are in fact ridiculous and cannot change. Comedy is anything which makes you laugh.
>
> (Àwàdà jẹ́ ọ̀kan lára ẹ̀yà eré-oníṣe tí ó ti wà tipẹ́. Ó jẹ́ èyí tí ó ṣe àfihàn àbùdá ènìyàn tí kò ṣe é yí padà. Àwàdà ni a gbà gẹ́gẹ́ bí ohunkóhun tí ó lè dá ẹ̀rín pani).

Okùn a-lọ́-má-jàá ni ó wà láàrin àwàdà àti ẹ̀rín rínrí nítorí ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ pé àwọn nǹkan tí oríkì àwọn ènìyàn wọ̀nyí sinmi lé ni akitiyan láti mú àwùjọ rẹ́rìn-ín, èyi tí ó fi hàn pé má-yà-mí ni àwàdà àti ẹ̀rín rínrín. Bámidélé (2001:2) rí àwàdà gẹ́gẹ́ bíi:

> …*Comedy is seen as an imitation just as other forms of poetry but imitation of a base action in that genus of vice which causes laughter.*
>
> (...ìsínjẹ àwọn ẹ̀yà ewì ṣùgbọ́n tí ìsínjẹ ọ̀hún dá lórí ìṣẹ̀lẹ̀ kan pàtó tí ó ń ṣẹlẹ̀ láwùjọ, tí àgbékalẹ̀ àfihàn irú ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀ yóò mú ẹ̀rín wá.)

Bergson (1981: 328-332) ki àwàdà gẹ́gẹ́ bí:

> …*an imitation of life, a glass of custom, an image of truth. Comedy holds the mirror up to nature and reflects things as they are to the end that society may recognize the extent of its shortcomings and the folly of its improvements.*
>
> (...ìsínjẹ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ojú ayé, àwòjíìji àṣà àti àwòrán òdodo. Àwàdà máa ń ya àwòrán bì ohun gbogbo ṣe rí ní

àwùjọ, ó sì máa ń jẹ́ kí àwùjọ rí àìṣedéédé àti ìwà òmùgọ̀ rẹ̀, èyí tí ó jẹ́ ìdènà fún ìdàgbàsókè.)

Trypanis nínú Adélékè (2020) náà ki àwàdà gẹ́gẹ́ bí ọmọ inú lítíréṣọ̀ nínú èyi tí aláwàdà ti máa ń fi àgbékalẹ̀ rẹ̀ sọ òkodoro ọ̀rọ̀ tàbí wo ìṣẹ̀lẹ̀ àyiká láti fi dánilẹ́kọ̀ọ́ ní ọ̀nà tí kò ní mú wàhálà bá òun tí ó sọ ọ́. Àwàdà ni Adélékè (2020) gbà gẹ́gẹ́ bí ọ̀gangan ipò ìjẹyọ ìṣeré aláwàdà. Ìdí rẹ̀ rè é tí a fi ń pè wọ́n ni ẹ̀dá-itàn apani-lẹ́rìn-ín, oníyẹ̀yẹ́, adánilárayá àti amúnifẹyín. Ní tòotọ́, tí a bá fi ojú inú wo ohun tí George Meredith sọ, tí Adélékè náa si kín in lẹ́yìn, a ó rí i pé àwàdà jẹ́ àgbékalẹ̀ tó jọni lójú, tó sì ṣè irànwọ́ fún ẹ̀rín. Àwàdà ṣíṣe máa ń fa ẹ̀rín rínrín ni; bí àwàdà bá jáde, ẹ̀rín rínrín ni ó máa ń tẹ̀lé e. Tí a bá tún wo ohun tí Trypanis sọ nípa pé àwàdà jẹ́ òkodoro ọ̀rọ̀ tàbí ọ̀nà láti dánilẹ́kọ̀ọ́ ní ìbámu pẹ̀lú oríkì Bergson pé àwàdà jẹ́ ọ̀kan gbòógì lára ohun tí a fi ń dẹ́kun ìwà ibàjẹ́ ní àwùjọ, a ó rí i pé bí àwàdà bá jáde gẹ́gẹ́ bíi pẹ̀tẹ̀pẹ́tẹ̀ tí a nà ní pọ̀pá; ó máa ń pe àkiyèsí àwọn ènìyàn àwùjọ sí ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀, ní èròngbà pé kí wọ́n tún ibẹ̀ ṣe. Iṣẹ́ ìwádìí yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé kì í ṣe gbogbo ìgbà tí àwàdà bá wáyé ni ó máa ń pani lẹ́rìn-ín, pàápàá tí ó bá jẹ́ àwàdà akọ. Èyí mú kí iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe àfikún oríkì àwàdà gẹ́gẹ́ bí àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀ tí a ṣe ní ọ̀ṣọ́ nípa ṣíṣe àmúlò ọgbọ́n, ìmọ̀, òye, ìrírí, ìhùwàsí àti ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ, láti ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ ní ọ̀nà tí yóò gbà mú olùgbọ́ lọ́kàn, tí yóò sì jọ wọ́n lójú fún ìpanilẹ́rìn-ín, ìdánilárayá, ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìtalólobó fún ohun tí ó ń fẹ́ àtúnṣe.

### 3.2 Ibi tí Iṣẹ́ dé Dúró Lórí Àwàdà

Lára àwọn onímọ̀ tó ti ṣiṣẹ́ lórí àwàdà ni Àlàbá (2016), Adéjùmọ̀ (2013), Raj (2012) àti Bámidélé (2000). Ojú ìwòye àwọn onímọ̀ wọ̀nyí lórí ohun tí àwàdà jẹ́ ni pé ọmọ inú lítíréṣọ̀ ni àwàdà, ó si lè panilẹ́rìn-ín, àmọ́ ó gbọ́dọ̀ ní àgbékalẹ̀ tí ó gún régé, tó sì jẹni lọ́kàn. Mordi (2020:112-114) ní tirẹ̀ jẹ́ kí ó yé wa pé kò sí bí a ṣe fẹ́ sọ ọ̀rọ̀ àwàdà kí a má sọ̀rọ̀ nípa kọ́mẹ́dì nítorí pé nǹkan kan náà ni wọ́n jẹ́. Mordì gbà pé àwàdà jẹ́ ẹ̀ka eré-oníṣe tí ó dá lórí ìpanilẹ́rìn-ín láti ara ìṣẹ̀lẹ̀, ìmọ̀lára àti èrò nǹkan tí a mọ̀ láwùjọ, a sì máa ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ẹ̀dá-ìtàn tí ó máa ń lo èdè ojoojúmọ́ láti fi gbé èrò wọn jáde. Iṣọ̀lá (2008: 1-20) fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwàdà ṣíṣe máa ń mú inú ènìyàn dùn, ó máa ń dẹ́rìn-ín pòṣónú, ó sì máa ń mú ọkàn tó gbọgbẹ́ tàbí ọkàn tó ń ṣàárẹ̀ lára dá. Ojú ìwòye Trypanis nínú Adélékè (2020:118-138) àti Bergson (1981:328-332) yàtọ̀ díẹ̀ sí ti àwọn onímọ̀ tókù. Àwọn onímọ̀ wọ̀nyí rí àwàdà gẹ́gẹ́ bí òkodoro ọ̀rọ̀ tí a gbé kalẹ̀ láti fi dẹ́kun ìwà ìbàjẹ́ ní àwùjọ. Iṣẹ́ ìwádìí yìí gbà pè àkójọpọ̀ àwọn ìrírí, ìmọ̀, ìhùwàsí tàbí àkíyèsí

àwọn ènìyàn àti ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ ni àwọn aláwàdà máa ń ṣà jọ láti ṣẹ̀dá tàbí gbé àwàdà kalẹ̀ ní ìlànà ojúkojú, alohùn tàbí àkọsílẹ̀ fún ìdánilárayá, ìdẹ́rìn-ín pani, ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ẹ̀kọ́ ìwà ìkóra-ẹni-ní-ìjánu nípa ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ. Iṣẹ́ ìwádìí yìí wòye pé kò tíì fi bẹ́ẹ̀ sí onímọ̀ kan tí ó ṣì wo àwàdà gẹ́gẹ́ bí ohun èlò fún yíyanjú ìṣòro ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ nínú ìdílé, ìdí nìyí tí iṣẹ́ ìwádìí yìí fi ṣe àyẹ̀wò bí ìlò àwàdà ṣe lè yanjú ìṣòro ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ajẹmọ́dìílé, tí èyí yóò sì jẹ́ kí àlàáfíà jọba ní àwùjọ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àwọn ìwé àyẹ̀wò.

### 3.3 Oríṣi Àwàdà

Oríṣi ọ̀nà méjì ni iṣẹ́ ìwádìí yìí pín àwàdà sí, èyí ni àwàdà akọ àti àwàdà abo. Àwàdà akọ ni iṣẹ́ ìwádìí yìí gbà pé àgbékalẹ̀ rẹ̀ kì í dùn mọ́ olùfaragbà nínú. Ohun tí a bá pè ní akọ máa ń le, ó sì máa ń ní agbára. Àwàdà akọ lè gbomijé lójú olùfaragbà, ó lè dá ìjà sílẹ̀, ó sì lè mú ọ̀rọ̀ agídí wá. Àgbékalẹ̀ àwàdà akọ máa ń sáábà jẹ́ èyí tí a fi òtítọ́ inú gbé jáde tàbí èyí tí a gbé jáde nípa ìlò ẹ̀dà ọ̀rọ̀. Àpẹẹrẹ èyí ni kí ènìyàn béèrè ìbéèrè nípa nǹkan tí kò yé e, ká wá dá a lóhùn lọ́nà akọ, tí èyí sì lè fa ìbínú.

**Ìbéèrè:** Ta ló gbé aṣọ yìí síbí?

**Ìdáhùn:** Tájù ọkọ Táwà tí ń gbé Tótoró ni ì.

Àwàdà abo ní tirẹ̀ kì í fi bẹ́ẹ̀ ní wàhálà nínú, kì í lani-lóòógùn, kì í sì mú inú bíni. Gbogbo ọ̀rọ̀ tí ó bá lè pani lẹ́rìn ín, dunni nínú tàbí dánilẹ́kọ̀ọ́ ni a mọ̀ sí àwàdà abo. Ó lè jẹ́ ìyakọ jíjẹ́, àwàdà àwaarawa, ìfara-ẹni-ṣàwàdà tàbí ìṣàwàdà-gbé-tìjú-tà.

### 3.4 Ààlà Láàrin Ẹ̀fẹ̀ àti Àwàdà

Bí a bá gùnlé oríṣiríṣi iṣẹ́ tí àwọn onímọ̀ ti ṣe lórí ẹ̀fẹ̀ àti àwàdà, iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe àkíyèsí pé ohun tí ó so àwọn méjèèjì pọ̀ tí ó sì jẹ wọ́n lógún jù ni ẹ̀rín rínrín àti ìlò èdè lọ́nà àrà. Iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe àkíyèsí pé ìṣàmúlò ẹ̀rín rínrín mú kí ààlà ṣòroó pa láàrin ẹ̀fẹ̀ àti àwàdà nítorí pé bí àwọn onímọ̀ kan ṣe gbà pé kò sí ààlà kankan láàrin ẹ̀fẹ̀ àti àwàdà, tí wọ́n gbà pé iṣẹ́ kan náà ni àwọn méjèèjì jọ ń jẹ́ fún àwùjọ náà ni àwọn kan sọ pé ààlà wà ní ààrín wọn. Lára àwọn onímọ̀ tí ó gbà pé kò sí ààlà láàrin ẹ̀fẹ̀ àti àwàdà ni Bergson (2003), Okafor (2015:74) àti Àlàbí (2021:143-162). Àwọn onímọ̀ wọ̀nyí gbà pé nǹkan kan náà ni àwọn méjèeji nítorí iṣẹ́ kan náà ni wọ́n jọ ń jẹ́ fún àwùjọ. Bí ẹ̀fẹ̀ ṣe ń kó ipa ribiribi nínú ètò ìfọ̀lúmọ̀ náà ni àwàdà ń sa ipá tirẹ̀ láti ṣàtúnṣe ìwà ìbàjẹ́ ní àwùjọ àti pé àwọn ẹ̀yà méjèèjì ni ó ní àbùdá ìpanilẹ́rìn ín tí ó máa ń ṣí aṣọ lójú eégún ìwà ìbàjẹ́. Lára àwọn onímọ̀ tí wọ́n gbà pé àalà wà láàrin ẹ̀fẹ̀ àti àwàdà ni Abrams (1999), Adéjùmọ̀

(2001:10-65) àti Raj (2012: 65-72). Ojúwòye àwọn onímọ̀ wọ̀nyí ni pé àwàdà kò ní àfojúsùn bí i ti ẹ̀fẹ̀ nítorí pé ohun tí ó ń sọ lè má jẹ́ẹ̀ òótọ́. Ẹ̀fẹ̀ máa ń ní àfojúsùn, ó sì máa ń fi òótọ́ ọ̀rọ̀ gún olùfaragbà lára ní èròǹgbà àtiṣe àtúnṣe tàbí jẹ́ àríkọ́gbọ́n fún àwùjọ. Ohun tí iṣẹ́ ìwádìí kíyèsí pé ó ya ẹ̀fẹ̀ sọ́tọ̀ kúrò lára àwàdà ni ṣíṣe ìkìlọ̀ ìwà àti ìbáwí lọ́nà tí ó le lórí àwọn ìwà tí ó tako ìtẹ̀síwájú àwùjọ. Iṣẹ́ ìwádìí yìí gbà pé àwàdà náà lè ṣe àfọ̀mọ́ àwùjọ dé àyè kan, àmọ́ ó fara mọ́ èrò àwọn onímọ̀ bí i Abrams (1999), Adéjùmọ̀ (2001) àti Raj (2012) pé ààlà wà láàrin ẹ̀fẹ̀ àti àwàdà.

**4. Ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ Ajẹmọ́dìílé**

Gẹ́gẹ́ bí ìtàkùn àgbáyé ṣe sọ, ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ajẹmọ́-ìdílé ni a lè pè ní àjọṣepọ̀ tí ó wà láàrin mọ̀lẹ́bí tí okùn ìbí so papọ̀ tí okùn ìbí yìí sì lè wá láti ìdílé bàbá tàbí ìyá. *https://www.focusonthefamily.com.* Ìfẹ́, ìṣọ̀kan àti àlàáfíà nínú ìdílé jẹ àwùjọ Yorùbá lógún púpọ̀ gégé bí Adéoyè (1979: 260-278) ti fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀. Wọn kì í fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú ọ̀rọ̀ ètò mọ̀lẹ́bí nítorí wọ́n gbà pé ilé ni a ti ń kẹ́ṣọ̀ọ́ ròde. Ìdí rèé ti wọ́n fi máa ń rí i dájú pé wọ́n fi ojú ọmọ mọ àṣà àti ìṣe, kí ó lè tayọ láàrin àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ ní àwùjọ. Ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ajẹmọ́dìílé ni a lè pè ní ìbágbépọ̀ ọkọ, aya, ọmọ, ẹbí, mọ̀lẹ́bí tàbí ojúlùmọ̀, tí ó ṣeéṣe kí wọ́n jọ máa gbé nínú ilé kan tàbí àyíká kan náà. Bí wọn kò bá sì gbé ní àyíká kan náà, ó ṣeé ṣe kí okùn ìbí so wọ́n pọ̀ ní ọ̀nà kan tàbí òmíràn. Adágbádá (2014:63) jẹ́ kí ó yé wa pé ní ayé àtijọ́, àjọṣepọ̀ tí o gún régé wà láàrín mọ̀lẹ́bí, pàápàá nípa ìtọ́jú ọmọ ní àwùjọ Yorùbá. Ìgbàgbọ́ wọn ni pé, àjòjí ọwọ́ kan kò gbẹ́rù dórí àti wí pé ojú méjì ní í bímọ, igba ojú ní í báni wò ó. Èyí mú kí ẹ̀mí ìṣọ̀kan rinlẹ̀ láwùjọ, tí ayé rójú, tí ayé sì ráyè. Adágbádá tẹ̀ síwájú pé lára àǹfààní ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ajẹmọ́dìílé ni; ìtọ́jú àti ààbò, ìdùnnú, ayọ̀, ìṣọ̀kan, àǹfààní ẹ̀kọ́ ìwé tàbí ẹ̀kọ́ṣẹ́ ọwọ́, ìbánikẹ́dùn, ìgbani-nímọ̀ràn, gbígbárùkù ti ara ẹni àti yíyanjú ìṣòro tí ó wù kí ó yọjú láàrin mọ̀lẹ́bí. Yàtọ̀ sí èyí, Adéfowópè (2014:30-46) fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn òbí ní àwùjọ Yorùbá máa ń sa ipá wọn láti fojú àwọn ọmọ wọn mọ àṣà àti ìṣe ilẹ̀ wa; bí àpẹẹrẹ, kíkọ́mọ ní àṣà ìbọ̀wọ̀fún, ìtẹpámọ́ṣẹ́, níní ìtẹ́lọ́rùn, ìpamọ́ra, ìranra-ẹni-lọ́wọ́ àti bí wọn yóò ṣe jẹ́ adarí rere lẹ́yìnwá ọ̀la. Ní sáà bágbàmu yìí, àṣà ìgbàlódé ti yí àṣà ilẹ̀ wa padà, tí èyí sì ti ṣe àkóbá ńlá fún àṣà àti ìṣe wa. Gẹ́gẹ́ bí a ti mọ̀, kò sí bí a ṣe lè rìn kí orí má mì. Níwọ̀n ìgbà tí àwọn ènìyàn tì ń ní ìbáṣépọ̀ pẹ̀lú àṣà àtọ̀húnrìnwá, pàápàá nínú ètò ìdílé, ó di dandan kí àwùjọ ní ìrírí àwọn ìwà ìbàjẹ́ bí irọ́ pípa, ìfojútẹ́ńbẹ́lú ẹni, ìfẹ̀mí òkùnkùn báni jà, òlè, àgbèrè àti pánṣágà, àìnímọ̀ọ̀tótó, ìjà, ìmẹ́lẹ́, oògùn ìkà ṣíṣe, àìnítẹríba fọ́kọ, àìlẹ́kọ̀ọ́-ilé, àìgbọràn, ìwà jàgídí-jàgan, ìpáǹle, ojúkòkòrò, lílo ọmọ ọ̀dọ̀ ní ìlòkulò àti àwọn ìwà kò-tọ́ mìíràn

gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹ yọ nínú àwọn ìwé tí iṣẹ́ ìwádìí yẹ̀ wò, *Nítorí Owó* tí Ìsọ̀lá kọ àti *Ìyá Yáàdì* tí Dòsùnmú kọ. Ìgbàgbọ́ àwọn òǹkọ̀wé àṣàyàn fún iṣẹ́ yìí ni pé ìwà ìbàjẹ́ tí àṣà àtọ̀húnrìnwá kó wọ àwùjọ wa ni ó ṣe àkóbá ńlá fún ìmúgbòòrò àwùjọ.

## 5. Ìtàn Inú àwọn Ìwé Àmúlò ní Ṣókí

### 5.1 *Nítorí Owó*

Iṣẹ́ tí ó bọ́ lọ́wọ́ Àdìó ni ó sọ ọ́ di ẹni yẹpẹrẹ lójú Àbẹ̀ní, aya rẹ̀. Owó tí Àdìó kò ní lọ́wọ́ kò jẹ́ kí ó tó ọkọọ́ ṣe lọ̀ọ̀dẹ̀. Tọ́rọ́-kọ́bọ̀ tí Àbẹ̀ní ń rí mú wá sílé nídìí ọjà wóróbo tí ó ń tà àti àgbàtà ọjà àwìn tí ó ń gbà láti ọ̀dọ̀ Àlàájà Àdíjátù ni wọ́n fi ń jẹun, èyí mú kí Àbẹ̀ní sọ ara rẹ̀ di apàṣẹ-wàá nínú ilé. Àtijẹ-àtimu tí ó wọ Àbẹ̀ní lọ́rùn, tí àtirán Oyèládùn, ọmọ kan ṣoṣo tí wọ́n bí lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ sì dogun ni ó mú kí ó gbèrò láti fi ọmọ rẹ̀ sí ibi-iṣẹ́ ọmọ-ọ̀dọ̀ ní ilé olóyè Ọládẹ̀jọ láìsọ fún Àdìó ọkọ rẹ̀. Àìlera ìdílé Àdìó nípasẹ̀ àìlówó lọ́wọ́ ni ó mú kí Àbẹ̀ní gbà fún Ọládẹ̀jọ láti yàn án ní àlè, tí ìyẹn sì bẹ̀rẹ̀ sí níí jẹ ẹran-sùnkùn-sí ní ara rẹ̀. Ọládẹ̀jọ gba Àdìó sí iṣẹ mágbèélé, kí ó lè máa bá Àbẹ̀ní, aya rẹ̀ múfẹ̀ẹ́ nígbà tí ìyẹn bá ti tẹ̀lé ọkọ̀ lọ sí ìrìn-àjò. Àdíjátù, ìyàwó Ọládẹ̀jọ gba Òyéládun gẹ́gẹ́ bí ọmọ-ọ̀dọ̀, ó sì ń ṣe é báṣubàṣu. Àṣé bí Ọládẹ̀jọ ṣe ń bá ìyàwó Àdìó múfẹ̀ẹ́ ìkọ̀kọ̀ ni Àdìó náà ń bá ìyàwó Ọládẹ̀jọ múfẹ̀ẹ́ ìkọ̀kọ̀. Ọ̀rọ̀ wá di hùn-ùn.

### 5.2 *Ìyá Yáàdì*

Agbára káká ni Àlùfáà Ilésanmí àti ìdílé rẹ̀ fi ń rí oúnjẹ òòjọ́ jẹ tẹ́lẹ̀ nídìí iṣẹ́ Olúwa tí ó ń ṣe. Ṣàdédé ni nǹkan yí padà sí rere fún Àlùfáà láìmọ̀ pé ìyàwó òun, Ìyá Yáàdì ni ó wá wọ̀rọ̀kọ̀ fi ṣàdá nípa dídara pọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ àjẹ́, tí wọ́n pe ara wọn ní ẹgbẹ́ Májẹ̀ẹ́óbàjẹ́. Ìyá Yáàdì bẹ̀ àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ pé kí wọ́n ran iṣẹ́ ìránṣẹ́ ọkọ òun lọ́wọ́, kí èrò le è máa wọ́ ní ilé ìjọsìn wọn. Gbogbo ohun tí Ìyá Yáàdì bèèrè lọ́wọ́ ẹgbẹ́ Májẹ̀ẹ́óbàjẹ́ ni wọ́n ṣe fún un àmọ́ wọ́n béèrè ẹ̀jẹ́ lọ́wọ́ rẹ̀. Àlùfáà kò fàyè gba Ìyá Yáàdì láti máa jẹ gàba lórí òun, èyí ni ó fa yánpọnyánrin láàrin tọkọtaya. Ẹ̀sùn tí Ìyá Yáàdì kà sí ọkọ rẹ̀ lọ́rùn ni pé àwọn obìnrin ẹlẹ́sẹ̀ ṣóóṣòòṣóó tí ó máa ń wá gbàdúrà lọ́dọ̀ Àlùfáà ti pọ̀ jù, ó ní wọ́n lè gba ọkọ mọ́ òun lọ́wọ́ nítorí ó rò pé ohun tí a bá fi sílẹ̀ lẹnu ewúrẹ́ ń tó. Ẹ̀sùn mìíràn ni pé Àlùfáà kò fi ọmọ wọn, Ọmọlabí jẹ oyè Àlùfáà nítorí ìwà ìbàjẹ́ tí ó wà lọ́wọ́ ọmọ náà, tí ó sì rò pé ayé ń ṣe irú rẹ̀. Bákan náà, Ìyá Yáàdì sọ Èyítáyọ̀, ọkọ ọmọ rẹ̀ di gbẹ̀wù-dání fún ọmọ rẹ̀, Adérọ́pò, ó sì sọ ọkọ rẹ̀, Àlùfáà di afọ́jú àti arọ tí ìyẹn di ta-ń-wọlé.

## 6. Ìṣòro Ìbára-Ẹni-Gbé-Pọ̀ Ajẹmọ́dìílé nínú Ìwé *Nítorí Owó* àti *Ìyá Yáàdì*

Ohun tí a fẹ́ ṣe níhìn-ín ni ṣíṣe àgbéyẹ̀wò bí àwọn òǹkọ̀wé ṣe ṣàfihàn oríṣiríṣi ìwà kò-tọ́ tí ó máa ń jẹ yọ nínú ìdílé, tí èyí sì ń dí ìtẹ̀siwájú ìtẹ̀síwájú àwùjọ lọ́wọ́. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni kì í sí àgbọ́yé àti àsọyé nínú ìdílé, aya kì í gbọ́ ti ọkọ, ọkọ náà a si sọ ara rẹ̀ di àmọ̀tẹ́kùn nínú ilé. Èyí máa ń ní ipa tí kò dára nínú ìgbé ayé àwọn ọmọ, tí ó sì lè mú kí wọ́n ya iyàkuyà. Irú àwọn ọmọ bẹ́ẹ̀ kì í wúlò fún yálà ẹbí, ara wọn tàbí àwùjọ. Lára àwọn iṣòro tí ó ń kojú ìdílé ni a ti rí;

### 6.1 Ìṣòro Àìnítẹ̀ríba fún Ọkọ

Gbogbo ẹ̀sìn ni ó fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ọkọ ni olórí aya. Ìkọ̀ọ̀kan wọn ni ó sì gbọ́dọ̀ mọ ojúṣe rẹ̀ nínú ìdílé fún ìbáṣepọ̀ tí ó dán mọ́ràn. Nínú *Ìyá Yáàdì*, ó hàn kedere pé kò si ìbáṣepọ̀ tí ó dán mọ́rán láàrin àlùfáà àti ìyàwó rẹ̀, Ìyá Yáàdì. Lóòótọ́ ni Ìyá Yáàdì gba àjẹ́ nítorí kí ọkọ rẹ̀ lè di olókìkí àti pé kí iṣẹ́ àmì àti iṣẹ́ ìyanu lè máa ṣẹlẹ̀, kí èrò sì máa wọ́ nínú ìjọ. Ó hàn kedere pé oore ẹ̀dẹ ni Ìyá Yáàdì ṣe fún ọkọ rẹ̀ nítorí ṣe ni ó lọ́ṣòó ti oore tí ó ṣe. Kò fi ọkọ rẹ̀ lọ́kàn balẹ̀, àṣẹ tí ó bá sì pa ni ó máa ń fẹ́ ki abẹ gé.

**Ìyá Yáàdì:** (*ó ké mọ́ ọkọ rẹ̀*) Dákẹ́ ńbẹ̀! Kí lò ń sọ tí kò dùn lẹ́nú ẹ yìí? Gbẹ́dó gbẹ́dó ti gbẹ́dó tán, ó kù sọ́wọ́ gbẹ́nugbẹ́nu. Kí ni wọn yóò sọ pé ó ṣe wọ́n tí wọn kò ní fi ọmọ mi joyè àlùfáà?

(Dòsùnmú 2004:13)

Nínú *Nítorí Owó,* òǹkọ̀wé ṣàfihàn Àbẹ̀ni gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá-ìtàn tí kò ní ìtẹ̀ríba fún ọkọ rẹ̀. Lóòótọ́ ni iṣẹ́ bọ́ lọ́wọ́ ọkọ rẹ̀, Àdìó, àmọ́ èyi kò ní kí ó máa fi ara ni ọkọ nínú ilé. Ọ̀rọ̀ kò-bá-kùn-gbé ni Àbẹ̀ní máa ń fi nu ọkọ rẹ̀ bí oúnjẹ, ti ó sì tún máa ń fi ebi pa á débi pé Àdìó máa ń jí gaàrí bù jẹ. Àìlówó lọ́wọ́ Àdìó ni ó sọ ọ́ di ọkọ yẹpẹrẹ ní ọ̀ọ̀dẹ̀. Àbẹ̀ní ni ó ń bọ́ ọkọ àti ọmọ pẹ̀lú ọjà wórobo tí ó ń tà. Ìwà àfojúdi Àbẹ̀ní ni ó mú ki ó fi Oyèládùn ọmọ wọn ṣe ọmọ-ọ̀dọ̀ fún Àdíjá láìjẹ́ kí ọkọ rẹ̀ mọ̀ nípa rẹ̀, èyí sì jẹ́ ọgbẹ́ ọkàn fún Àdìó. A rí àpẹẹrẹ èyí nígbà tí Oyèládùn kiri ọjà dé tí Àbẹ̀ní, ìyá rẹ̀ kò jẹ́ kí ó tètè jẹun. Àdìó, bàbá Oyèládùn rọ ìyàwó rẹ̀ pé kí ó jẹ́ kí ọmọ jeun tán kí ó tó ṣírò ọjà tí ó tà. Ọ̀rọ̀ à-gbọ́-sọgbá-nù ni Àbẹ̀ní bẹ̀rẹ̀ sí ní í sọ si ọkọ rẹ̀.

**Àdìó:** Ẹ̀ẹ̀ wa jẹ́ kọ́mọ yìí ó jẹun ná, látàárọ̀!

**Àbẹ̀ni:** Èétirí? Mo ní kò níí jẹun ni, àbi ọmọ tajà kó má jábọ̀? Abọ̀ là á jẹ́ ká tóó jẹun. Ibi tí a ti ń rówó tí a fi ń jẹun ọ̀hún náà rèé. Àbí ẹ̀ẹ̀ mọ̀?

**Àdìó:** Dákun o

**Àbẹ̀ní:** Ọ̀rọ̀ dákun kọ́. Ẹni tí ò rówó fi silẹ̀ kò tún lè máa dí mi lọ́wọ́ ìwọ̀nba tí mo bá ń ṣe.

**Àdìó:** Mo ní o dákun, àbí?

**Àbẹ̀ní:** N ò dákun o. Bẹ́yin náà bá ń rí díẹ̀ fi silẹ̀, a ò níí máa sá ọmọ lóòrùn lójoojúmọ́ báyìí…Gbogbo àwọn ẹgbẹ́ yín tí wọ́n dá dúró lẹ́nu iṣẹ́ ti wá nnkan mìíràn ṣe. Àfi kí ẹ̀yin máa wá bá wa jà lórí ẹran tí kò sí lọ́bẹ̀.

(Ìṣọ̀lá 2014:5)

### 6.2 Ìṣòro Fífi Agbára Òkùnkùn Báni Jà

Láti ìgbà ìwáṣẹ̀ ni agbára òkùnkùn ti wà ní àwùjọ. Ipá tí àwọn ẹ̀mí àìmọ́ wọ̀nyí ń kó kì í fi bẹ́ẹ̀ mú ìtura bá àwùjọ. Àwọn ọmọ ẹgbẹ́ òkùnkùn wọ̀nyí ṣòroó dá mọ̀, àmọ́ àwùjọ kì í fẹ́ kó iyán wọn kéré nítorí wọn ò kọ̀ kí ilẹ̀ sú lọ́sàn-án gangan. Kò sí ibi tí ìyẹ́ àwọn ẹ̀mí àìrí wọ̀nyí kì í dé, ojú wọn kálé-káko. Ọ̀kan gbòógì lára àwọn ìṣòro tí ó ń mú ìfàsẹ́yìn bá àwùjọ, pàápàá, ìdílé ni fífi ẹ̀mí àìrí dí ìṣe-rere ọmọnìkejì lọ́wọ́. Nínú *Ìyá Yáàdì*, a rí bi àwọn ẹgbẹ́ àjẹ́ tí wọ́n pe ara wọn ní ẹgbẹ́ Májẹ̀-ẹ́-ó-bà-jẹ́ ṣe ń fi agbára òkùnkùn da ìdílé rú. Wọ́n fi àìsàn kọlu tọkọ taya Ọláòrebìkan, wọ́n si bá ayé wọn jẹ́ kanlẹ̀. A rí àpẹẹrẹ èyí níbi tí Jẹjẹrẹ ti ń jábọ̀ iṣẹ́ ìríjú rẹ̀ fún àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Májẹ̀-ẹ́-ó-bà-jẹ́:

**Jẹjẹrẹ:** Mo lọ. Mo bọ̀. N ò bọmọ jẹ́. Mo jiṣẹ́ tí ẹ rán mi. Mo fi imú àwọn tọkọtaya Ọláòrebìkan fọn fèrè. Mo dá ààrẹ̀ sí wọn lára. Àìsàn tí kò gbóogùn tí a mọ̀ sí éèdì ni mo fi kọ lù wọ́n.

(Dòsùnmú 2004:29)

Bakan náà, Ata Wẹ́wẹ́ tí ó jẹ́ ọ̀kan lára ọmọ ẹgbẹ́ lọ fi ejọ́ ìyá ọkọ rẹ̀ tí ó ń bá a ṣorogún lọ́ọ̀dẹ̀, tí kò sì jẹ́ kí ó fi ẹ̀dọ̀ lórí òróǹro sun àwọn ẹgbẹ́ àjẹ́. Abẹ́fẹ́lẹ́ tí ó jẹ́ olórí ẹgbẹ́ àjẹ́ fi ọkàn Ata Wẹ́wẹ́ balẹ̀ pé kò séwu lẹ́gbẹ̀rún ẹ̀kọ. Ó ní ìyà tó tọ́ ni wọn yóó fi jẹ ìyá ọkọ rẹ̀, ó sì rọ Wèrèpè láti lọ ṣe iṣẹ́ náà.

**Ata Wẹ́wẹ́:** Ọ̀rọ̀ ìyá ọkọ mi ni mo mú wá o. Kò jẹ́ kí ń gbádùn ọkọ mi. Kò sì fi mí lọ́kàn balẹ̀. Lẹ́nu ọjọ́ méta yìí ni ó tún sọ pé òun yóò fẹ́ ìyàwó fún ọmọ

òun. Nítorí náà, mo fẹ́ ki ẹ gbo ewúro sí i lójú, kí ẹ sì ṣe é bi ata ṣe ń ṣojú.

**Abẹ́fẹ́lẹ́:** Wèrèpè ò níbì kan à á gbámú, gbogbo ara níí fìí jóni wàìwàì. Ìwọ ni kí o lọ sí ilé Ata Wẹ́wẹ́, kí o da wèrèpè lu ìyá ọkọ rẹ̀, kí àìsàn kọ lù ú. Jẹ́ kí ó ṣàìsàn, kí wọ́n máa gbé e kírí ilé-ìwòsàn. Jẹ́ kí ó di fòní kú, fọ̀la dìde.

(Dòsùnmú 2004:8-9).

Àwọn ẹgbẹ́ Májẹ̀-ẹ́-ó-bà-jẹ́ rán Wèrèpè làti lọ ṣe ìyá ọkọ Ata Wẹ́wẹ́ ṣìbáṣìbo nítorí ó ń ni ọmọ ẹgbẹ́ wọn lára. Wèrèpé kọ́kọ́ sọ ìyá di alágànná, ó tún da ètè sí i lara, ní ìyá bá di èrò inú igbó. Ìwà ìkà tí àwọn ẹgbẹ́ àjẹ́ máa ń hù yìí máa ń dùn mọ́ wọn débi pé, olórí ẹgbẹ́ tún lè fi ìràwọ̀ kún ìràwọ̀ ẹni tí ó bá ṣiṣẹ́ rẹ̀ dáadáa láàrin ọmọ ẹgbẹ́.

**Wèrèpè:** Ìyá aláàánú, gẹ́gẹ́ bí ìṣe mi, mo kọ́kọ́ da wèrèpè sí i lára. Ní ó bá ń ṣe gán-án-gàn-àn-gán. Nìgbà tí ó yá ni mo dá ètè sí i lára. Ẹ sì mọ̀ pé kó sí adétè tí ó lè gbé láàrin ènìyàn.

(Dòsùnmú 2004:30)

Síwájú sí i, owú jíjẹ ni ó mú kí Ìyá Yáàdì sọ ọkọ rẹ̀ di ta-ń-wọlé, tí ó sì fi àìsàn dá a gúnlẹ̀ sí ojú kan. Ó ní àwọn obìnrin tí ó wá ń gbàdúrà lọ́dọ̀ ọkọ òun ti ń pọ̀ jù, òun ò sì níí jẹ́ ki wọ́n gba ọkọ lọ́wọ́ òun. Ó bẹ àwọn ẹgbẹ́ àjẹ́, tí òun náà jẹ́ ọ̀kan nínú wọn láti bá òun fi ẹ̀mí òkùnkùn dá sèríà fún ọkọ òun.

**Ìyá Yáàdì:** …àwọn ọmọbìnrin ẹlẹ́sẹ̀ ṣóóṣòòṣó kan a máa wá ọkọ mi wá láti gbàdúrà. N kò sì gbọ́dọ̀ la ojú mi sílẹ̀ kí tàlùbọ̀ kó wọ̀ ọ́, ni mo ṣe mú ẹjọ́ rẹ̀ wá sí ìpàdé ẹgbẹ́.

**Abẹ́fẹ́lẹ́:** Bí n ò bá gbàgbé, ohun tí ó fẹ́ ni pé kí a ṣẹ́ ọ̀pá oúnjẹ mọ́ ọkọ rẹ̀ lẹ́nu. Kí á dá a jókòó. Pé ibi tí ó wọ mọ́tò dé, kí ó fi ẹsẹ̀ rìn dé ibẹ̀.

**Ọkinni:** Bẹ́ẹ̀ ni, mo fẹ́ bẹ́ẹ̀. Kí ó wà nílé kí ó máa béèrè ohun tí ń ṣẹlẹ̀ lóde.

(Dòsùnmú 2004:64)

Bákan náà, Ìyá Yáàdì sọ ọkọ ọmọ rẹ̀, Èyítáyọ̀ di gbẹ̀wùdání fún Adéròpò, ọmọ rẹ̀. Ó gbé àgbààná ọtí mímu lé e lọ́wọ́, tí ìyẹn sì di ìyàwó dípò ọkọ nínú ilé.

**Ìyá Yáàdì:** …Ti ọkọ ọmọ mi ló kù…Kí ọmọ mi lè jẹ gàba lé e lórí ni mo ṣe gbé àgbàànà lé e lọ́wọ́ tí mo fi ẹ̀mí ọtí mímú dá a lọ́lá. Tí mo sí sọ ọ́ di gbẹ̀wùdání fún ìyàwó rẹ̀.

(Dòsùnmú 2004:65)

**6.3 Ìṣòro Lílo Ọmọ-Ọ̀dọ̀ ní Ìlòkulò**

Àwùjọ Yorùbá gbà pé ìbí a bẹ́rú náà ni a bí ọmọ, àmọ́ àwọn ènìyàn kan wà tí ó jẹ́ pé ìlòkulò ni wọ́n máa ń lo ọmọ-ọ̀dọ̀. Òwe àparò kan kò ga ju ìkan lọ kò ní ìtumọ̀ sí irú àwọn ìkà ẹ̀dá wọ̀nyí, ọmọ ọlọ́mọ ni wọ́n máa a ń rán nísẹ̀ dé tòrutòru. Nínú *Nítorí Owó*, òǹkọ̀wé ṣe àfihàn Àdíjá gẹ́gẹ́ bí oníkanra ẹ̀dá. Ìlòkulò ni ó lo Oyèládùn tí ó wá ṣe iṣẹ́ ọmọ-ọ̀dọ̀ ní ilé wọn nítorí àìrí owó ilé-ẹ̀kọ́ rẹ̀ san. Oyéládùn níí ṣe gbogbo iṣẹ́ ilé. Kò gbọ́dọ̀ gbọ́ pé Bọ̀sípò, ọmọ rẹ̀ ṣe iṣẹ́ kankan. Ó fẹ́rẹ̀ẹ̀ na Òyéládùn pa ní ọjọ́ tí àwo kan ṣèesì bọ́ fọ́ ní ọwọ́ rẹ̀. Kò sí èpè àti ọ̀rọ̀ kò-bákùn-gbé ti Àdíjá kò sọ sí ọmọ náà tán.

**Àdíjá:** (*Ó dide fìù*) Yéè! Ọmọ yìí ti fọ́ gbogbo àwo mi tán o? (*Ó ń sáré lọ sí kísìnnì*) Háà! Irú ọmọ wo nìyí o? Háà! Àwo yìí ló fọ́, ọmọ yìí! Àwo ẹgbẹ̀rún kan náírà ẹyọ kan, nítorí Ọlórun! Kín ló dé? Báwo lo ti ṣe é?

**Oyèládùn:** Ó yọ̀ bọ́ ni mà, ọsẹ ọwọ́ mi ló jẹ́ kó yọ̀ bọ́ mà.

**Àdíjá:** O ò rí i párungún ni ìwọ ọmọ olóríburúkú yìí? Kín lò ń wó tí àwo fi ń yọ̀ bọ́ lọ́wọ́ ẹ? (*ó ń nà án*). Olóríburúkú ni ọ́. Má dá mi ní gbèsè! Ẹni iyà!

**Oyèládùn:** (*Ó ń sunkún, ó ń bẹ̀bẹ̀ bí wọ́n ti ń nà án)* Ẹ dákun mà, ẹ dákun mà, ó ṣèèṣì ni mà… Mo ti fọ ìyókù tán mà…

**Àdíjá:** Kí ọmọkọ́mọ kan má run gbogbo àwo mi o. A à ri irú rẹ̀ rà mọ́ pàápàá.

(Ìṣọ̀lá 2014:53).

**6.4 Ìṣòro Kíkẹ́ Ọmọ ní Akẹ́bàjẹ́ Àti Àìleẹ̀kọ̀ọ́-Ilé**

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, ọmọ tí a kò bá kọ́ ní í gbé ilé tí a kọ́ tà. Ọ̀pọ̀ òbí ni wọ́n torí pé wọ́n ní owó, ti wọn kò fún ọmọ wọn ní ẹ̀kọ́-ilé tí ó yè kooro àti ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbi. Èrò wọn ni pé olówó

ṣe òhun gbogbo tán. Nínú *Nítorí Owó*, Àdíjá kẹ́ Bọ̀sipò, ọmọ rẹ̀ ní àkẹ́bàjẹ́ débi pé ṣe ni ìyẹn náà máa ń hùwà bí ó ṣe wù ú, tí ó sì máa ń jayé ọlọ́ba. Olódo ni Bọ̀sipò, ọlẹ̀ ni, kò sì mọ iṣẹ́ ilé Kankan-án ṣe. Kọ́míìkì nìkan ni ó mọ̀-ọ́n wò. Òǹkọ̀wé ṣàfihàn Bọ̀sípò gẹ́gẹ́ bí ọmọ tí kò lẹ́kọ̀ọ́-ilé. Ṣé ni ó ń bú Oyèládùn tí ó sì tún ń fi ọ̀rọ̀ rànṣẹ́ sí àwọn òbí rẹ̀, nítorí pé ìyẹn ní kí ó fọ abọ́ tí ó fi jẹun. O sọ ọ̀rọ̀ a-gbọ́-sọgbá-nù sí Oyèladùn, tí ìyẹn sì bẹ̀rẹ̀ sí ní í sunkún.

**Oyèládùn:** Ṣé o ò wá níí jẹun tán mọ́ ni? Màá gbé àwo o.

**Bọ̀sípò:** Níbo? Má danwò! Mi ì tí ì ṣe tán ni mo sọ.

**Oyèládùn:** A jẹ pé ìwọ lo máa fọ àwo tó kù o. Èmi ń lọ fọ ilẹ̀ nìyẹn.

**Bọ̀sípò:** Èèmi? Èmi á fọ àwo oúnjẹ? Nílé yìí kọ́. Níbo ni ìwọ wà? Mo mọ̀ pé oò mọ nǹkan tí ó ń sọ. Tí o bá jẹ́ kí Mọ́mì gbọ́ ohun tí o sọ yẹn, wà á jẹ iyán ẹ nísu. O ò sá mọ̀ pé iṣẹ́ owó ẹ lò ń ṣe ṣá!

**Òyèládùn:** Bí ò bá wọ̀ mọ́, máà padà lọ sí ilé wa, àbí.

**Bọ̀sípò:** llé wo? Kì í ṣe dádì ẹ ló tún wá gbaṣẹ́ níbí yẹn, àbi mọ́mì ẹ kọ́ ló jẹ wá lówó rẹpẹtẹ yẹn?

(Ìṣọ̀lá 2014:56)

Nínú *lyá Yáàdì*, ìyá Yáàdì kẹ́ Ọmọlabí ní àkẹ́bàjẹ́, kò sì kọ́ ọ ní ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí nítorí pé òun nìkan ni ọmọkùnrin tí ó bí. Kò rí ohun tí ó burú nínú gbogbo ìwà ibàjẹ́ tí ọmọ rẹ̀ ń hù nítorí ó rò pé ayé ń ṣe irú rẹ̀. Kò sí ẹni tí ó lè bá Ọmọlabí wi. Èrò rẹ̀ sì ni pé kí ọmọkùnrin kan ṣoṣo tí òun bi joyè àlùfàà ní èròngbà àtijogún ìjọ bí àlùfáà bá papò dà. Àlùfáà tako èrò ìyá Yáàdì, ó ní yóò ṣòro láti fi Ọmọlabí joyè àlùfáà nítorí ìròyìn yóò ti dé ọ̀dọ̀ àwọn aláṣẹ ìjọ nípa àwọn ìwà búburú tí ọmọ wọn ń hù. Ó ní wọ́n ti kìlọ̀ fún ọmọ wọn títí ṣùgbọ́n kò gbọ́. Inú ìyá Yaàdi kò dùn sí èsì tí ó gbọ́ lẹ́nu ọkọ rẹ̀.

**Àlùfáà:** Kò sì ju àwọn ìwà tí ọmọ yìí ń hù nínú ìjọ lọ.

**Ìyá Yáàdì:** Kí ló ṣe tí ẹni kan kò ṣe rí? Bí ó tilẹ̀ jalè, owó tó gbé kì í ṣe tẹnìkan. Bí ó tilẹ̀ fún ọmọ bàbá ijọ lóyún, ṣe èyí ni ojú ò rí rí ni, àbí èyí jẹ́ ohun tí etí ò gbọ́ rí? Ṣé ọmọ ẹlòmíràn kò ṣe irú èyí rí? Jọ̀wọ́, ìyẹn kò jẹ́ titun. Bí ó bá dépò àlùfáà, yóò yí padà.

(Dòsùnmú 2004:13-14)

**6.5 Ìṣòro Àinímọ̀ọ́tótó**

Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé ìmọ́tótó ló lè ṣẹ́gun àrùn gbogbo àti pé ọ̀bùn ni wọn ka ẹni tí kò tọ́jú ilé àti àyíká rẹ̀ dáadáa sí. Nínú *Nítorí Owó*, Àbẹ̀ní dọ́gbọ́n fi ara rẹ̀ ṣàwàdà pé ọ̀bùn ni òun, nígbà tí Àdíjá wá a wá si ilé. Bí ó ṣe ní kí Àdíjá jókòo, ni ó rí i pé àga tí ó ní ki àlejò jókòó sí dọ̀tí, tí èyí sì tì í lójú, ọgbọ́ọgbọ́n ni ó fi pé ọmọ rẹ̀ pé kí ó wá fi àkísà nu àgà náà. Ó ní:

> Aà, ẹ dákun, ẹ jókòó…ẹ dúró ná…Òyèládùn, mú àkísà kan ki o
> nu oríi àgà nù. (*Oyèládùn mú àkísà kan ó fẹ́ẹ́ fi nu aga…)*
>
> *(*Ìṣọ̀lá 2014: *7)*

**6.6 Ìṣòro Ìfojú-Tẹ́ńbẹ́lú Ènìyàn**

Gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ àwọn àgbà, ohun tí ó kojú sí ẹnìkan, ẹ̀yìn ló kọ sí ẹlòmíràn bí ìlù gángan. Ní ìgbà mìíràn, ẹni tí ó ní orí kì í ní filà, ọwọ́ Ọlórun sì ni ìrìn-àjo ẹ̀dá láyé wà. Bí ènìyàn bá wà ní ipò kan lónìí, kí ó má rò pé mímọ̀-ọ́n ṣe òun ni. Nínú *Nítorí Owó*, Oyèládùn mọ̀wé, àmọ̀ àwọn òbí rẹ̀ kò ní owó láti tọ́ ọ ní ẹ̀kọ́-ìwé, èyí mú kí ó máa ṣe iṣẹ́ ọmọ-ọ̀dọ̀ ní ọ̀dọ̀ olóyè Ọládẹ́jọ, bàbá Bọ̀sípò. Olówó ni olóyè Ọládẹ́jọ̀, ó rí òwó tọ́ ọmọ rẹ̀ ní ẹ̀kọ́-ìwé, àmọ̀ ìwà ìmẹ́lẹ́ Bọ̀sipò kò jẹ́ kí ó mọ ìwé. Bọ̀sípò rò pé iṣẹ́ ọmọ-ọ̀dọ̀ tí Oyèládùn ń ṣe kò le è jẹ́ kí ó ní ìmọ̀ ẹ̀kọ́-ìwé. Bọ̀sípò fi Oyèládùn ṣàwàdà, nígbà tí ìyẹn ní òun lè bá a ṣe iṣẹ́ àṣetiléwá tí wọ́n fún un lórí ìmọ̀ ìṣirò.

> …Wò ó, o ò lè gba ẹyọkan níbẹ̀. Iṣẹ́ SSSl ni
> …(*ó rẹ́rìn-ín títí*) Nǹkan tí kò yé èmi alára!
>
> (Ìṣọ̀lá 2014:57)

**6.7 Ìṣòro Ìjà Jíjà**

Ìjà jíjà jẹ́ ara ìṣòro àwùjọ́ tí kì í sì mú ìtẹ̀síwájú àti ìdàgbàsókè bá àwùjọ. Kò sí ibi tí ìjà kò ti le è wáyé. Ó lè jẹ́ láàrin ọkọ àti aya, ọmọ àti òbí, ẹ̀bí sí ẹ̀bí, ibi iṣẹ́ tàbí ibi okòwò. Nínú *Ìyá Yáidi*, òǹkọ̀wé ṣàfihàn bí Adéróọ̀pò àti Ọláníyì, àbúrò ọkọ rẹ̀ ṣe fi ìjà pẹ́ẹ̀ta lórí bí ó ṣe sọ Èyítàyọ̀, ẹ̀gbọ́n rẹ̀ di gbẹ̀wù-dání, tí ìyàwó sì jẹ gàba lórí ọkọ. Èyitáyọ̀ ní í fọṣọ, òun ní í lọṣọ, òun kan náà ní í sebẹ̀. Ìgbà tí àbúrò rẹ̀ wá kí wọn ni àṣírí tú, tí Ọláníyì sì fi àìdunnú rẹ̀ sí èyi hàn pé kò bòjú

mu, kò tilẹ̀ bá àṣà Yorùbá mu pé ọkọ ni ó ń ṣe gbogbo iṣẹ́ ilé. Adérọ́pò kò rí òun tí ó burú nínú èyí, ìjà ni ó gbé ko àbúrò ọkọ rẹ̀ lójú.

**Adérọ́pò:** Ẹ jọ̀wọ́ ẹ má jẹ́ kí n láìfí yín o. Ẹ jẹ́ kí kan-in-kan-in ilé yín máa ta yín nídìí.

**Ọlániyì:** Ìyẹn èmi náà?

**Adérọ́pò:** Ẹ̀yin ni mò ń bá wi. N ò bẹ̀rù yín, mo kàn ń tijú yín ni. Ṣùgbọ́n éyi tí ẹ wá ṣe yìí ni n ó fi mú ìtìjú kúrò.

**Ọlániyì:** Ṣé ẹ gbọ́ ohun tí iyàwó yín ń sọ? Ẹ sì dákẹ́, ẹ ò sọ̀rọ̀.

**Adérọ́pò:** Ẹ jọ̀wọ́ bùrọ̀dá, ẹ wá máa lọ. Ẹ má da ilé wa rú. Ilé tí ó bá ti tòrò ni èsù máa ń wọ́nà láti dàrú.

**Ọlániyì:** Ṣé èmi ni èṣù tí ó fẹ́ da ilé yín rú?

**Adérọ́pò:** Mi ò lè sọ o. Ẹ jọ̀wọ́ bí ẹ ò bá rí ọ̀rọ̀ sọ, ẹ wá máa lọ, ilẹ̀ ti ṣú. Akókò àtisùn ti tó.

(Dòsùnmú 2004:40-41)

Láì déènà pẹnu, a ó rí i pé àwọn ìṣòro tí a ṣe àlàkalẹ̀ wọn lókè wọ̀nyí kò ṣe àjòjì sí àwùjọ Yorùbá. Àwọn òǹkọ̀wé àfihàn wọn gẹ́gẹ́ bí ìṣòro tí kò jẹ́ kí ìtẹ̀síwájú dé bá àwùjọ. Àwàdà máa ń ṣe àmúlò ẹ̀rín láti ṣàfihàn ìwà kò-tọ́, tí yóò sì fi ọgbọ́ọgbọ́n sọ fún oníwà ibàjẹ́ pé ohun tí kò dára, kò dára.

## 7. Fífi Àwàdà Yanjú Ìṣòro Ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ Ajẹmọ́dìílé

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, bí ọ̀ọ̀dẹ̀ ò dùn, bí ìgbẹ́ ni ìgboro ó ri. Bí ìlù gángan, tí ó máa ń kọjú sí oníkálukú ni ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, ni ọ̀rọ̀ ìpènijà tí ó ń bá ìdìlé kọ̀ọ̀kan fínra rí. Oníruurú ìṣòro ni ó máa ń fara hàn nínú ìdìlé, tí èyí sì máa ń ní í ṣe pẹ̀lú ibáṣepọ̀ tí ó wà nínú ìdílé kọ̀ọ̀kan. Ìpèníjà ìdílé kọ̀ọ̀kan yàtọ̀ síra, oníkálùkù ìdílé ni ó sì mọ ọ̀nà tí ó ń gbà yanjú àwọn ìpèníjà wọ̀nyí, lọ́nà tí kò fi ní dí àlàáfíà àwùjọ lọ́wọ́. Àkíyèsi tí a ṣe nínú àwọn àṣàyàn ìwé àmúlò ni pé àwàdà ṣe àtúnṣe àwùjọ dé àyè kan, tí ó sì wá ojútùú sí àwọn ìṣòrò náà bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kì í ṣe gbogbo rẹ̀ ni ó wá ìyanjú sí, tí èyí sì jẹ́ kí ìdàgbàsókè àti ìtẹ̀síwájú dé bá àwùjọ.

### 7.1 Fífi Àwàdà Yanjú Aáwọ̀ àti Àìlẹ́mìí Ìdáríjì

Gẹ́gẹ́ bí a ti mọ̀ pé kò si a-rẹ́-má-jà, bẹ́ẹ̀ náà ni kò sí a-jà-má-rẹ̀ẹ́. Kì í fi bẹ́ẹ̀ sí àlàáfià nínú ìdìlé tí ọkọ àti aya bá ti ń ṣe ìjọba ara wọn lọ́tọ̀ọ̀tọ̀. Àwọn òǹkọ̀wé àmúlò lo àwàdà láti pẹ̀tù sí aáwọ̀ tí ó ṣẹlẹ̀ láàrin àwọn ẹ̀dá-ìtàn, èyí sì yanjú ìṣòro tí ó ń bá ìdìlé fínra, pàápàá láàrin ọkọ àti aya. Nínú *Ìyá Yáàdì*, Alùfáà fi ìwà àìní ẹ̀mí ìdáríjì àti àìní ìtẹ́lọ́rùn ọmọ rẹ̀, Adérọ́pò ṣàwàdà nípa kíkan àpótí ẹ̀sùn méjì fún òun àti ọkọ rẹ̀ wí pé kí oníkálukú máa ju ẹ̀sùn tí wọn bá ṣẹ ara wọn sí inú rẹ̀. Àìsí ẹ̀mí ìdáríjì yìí kò jẹ́ kí ìfẹ́ àti àlàáfià jọba nínú ìgbéyàwó Adérọ́pò àti ọkọ rẹ̀, Eyitáyò. Gbogbo ìgbà ni Adérọ́pò máa ń wá fi ẹjọ́ ọkọ rẹ̀ sun àwọn òbí rẹ̀ pé ó ń fi ìyà jẹ òun, èyi mú kí bàbá rẹ̀, Àlùfáà gbé ìgbésẹ̀ tí ó gbé. Alùfáà ní:

> …njẹ́ ẹ mọ̀ pé láti ọ̀sẹ̀ tí ó kọjá ni Adérọ́pò ti ń fa ìjàngbọ̀n nínú ilé? Nígbà tí wàhálà rẹ̀ pọ̀ lápọ̀jù ni mo kan àpótí méjì fún wọn pé kí olúkúlùkù máa kó ẹ̀sùn tí ó bá ní sí ẹnìkejì rẹ̀ sínú àpótí yìí.
>
> (Dòsùnmú 2004:33)

Adérọ́pò pàápàá fi ara rẹ̀ sàwàdà nípa kíkọ gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ tí ọkọ rẹ̀ ṣẹ̀ ẹ́ sínú àpótí láìmọ̀ pé ìwà àìní ẹ̀mí ìdáríjì òun ni àlùfáà fi ṣàwàdà. Adérọ́pò ní:

> (*ó gbé àpótí tirẹ̀ síta, ó ṣí i láti kó àwọn ẹ̀sùn tí ó ní sí ọkọ rẹ̀ jáde. Ó sì ń kàwọ́n sí etí àwọn òbí rẹ̀*). Ẹ̀sùn àkọ́kọ́ tí mo ní sí ọkọ mi ni pé ní ọjọ́ Àjé tí ó kọjá, mo ní kí ó gbé mi jade, ó kọ̀ jálẹ̀ pé ọ̀nà òun kò gba ibi tí mò ń lọ. Ní ọjọ́ Ìṣẹ́gun, mo gbé oúnjẹ kalẹ̀ fún un, ó sọ pé òun kò jẹ ẹ̀bà…Ní Ọjọ́rú, mo sọ pé kí á jọ lọ kí mọ́mì mi, ṣùgbọ́n kò bá mi lọ, ó ní mọ́tò kò dára. Ṣùgbọ́n nígbà tí yóò fi wọlé láti ibi tí ó lọ, ó ti mutí yó. Ni Ọjọ́bọ̀, mo ní kí a jọ wọ irú aṣọ kan náà, ó kọ̀ jálẹ̀ pé aṣọ tòun kò sí ní lílọ̀. Ní ọjọ́ Ẹtì, mo ní kò gbọdọ̀ lọ sí ìṣọ́ òru pé kí ó sùn sí ilé; àfi ìgbà tí ó lọ si ìsọ́ òru náà. Ní òní tí i ṣe ọjọ́ Àbámẹ́ta, mo sọ pé kí á lọ sí ibi ayẹyẹ ọjọ́ ibí ọ̀rẹ́ mi, Adébímpé, ó ni n ò tètè sọ fún òun nítorí náà òun kò níí bá mi lọ.
>
> (Dòsùnmú 2004::33-34)

Àwàdà tí Èyitáyọ̀ fi aya rẹ̀ tí ó ka gbogbo ẹ̀sùn ayé àti ọ̀run sí i lọ́rùn ṣe ni pé ìfẹ́ ni àkójá òfin, àti pé bí ìfẹ́ bá wà ní àwùjọ, a kò níí ṣẹ ara wa dàbí alárà. Ó ní:

> Adérọ́pò aya mi, nítorí pé mo ní ìfẹ́ rẹ,
> ń kò rí ẹ̀sùn kankan sí ọ rárá.

**ONDO JOURNAL OF ARTS**
**Faculty of Arts**
**Adeyemi Federal University of Education, Ondo**
OPEN ACCESS https://ojaafued.com/index.php/ojall ***Volume 1, Number 1, 2025***

(Dòsùnmú 2004:34)

Ìyàlẹ́nu ńlá ni èyí sì jẹ́ fún Adérọ́pò pé ọkọ òun kò rí àlèébù kankan lára òun. O ní:

> Èyítáyọ̀, pẹ̀lú bí mo ti ṣe sí ọ tó,
> o kò rí ẹ̀sùn kà sí mi lẹ́sẹ̀?

(Dòsùnmú 2004:34)

Àwàdà yìí pàápàá mú kí ìyá Yáàdì, tí ó ti ń gbè lẹ́yìn ìkà ọmọ rẹ̀ tẹ́lẹ̀ bẹ ọkọ ọmọ rẹ̀, ó ni:

> Jọ̀wọ́ ọkọ mi, dáríjì mi. Àṣìṣe gbáà ni.
>
> Mo rò pé o kò fẹ́ràn ọmọ mi ni.

(Dòsùnmú 2004:34)

Adérọ́pò náà bẹ ọkọ rẹ̀ fún àforíjì. Ìgbésẹ̀ yìí mú ki àlàáfià jọba padà nínú ẹbí wọn. Ó ní:

> (*Lórí ikúnlẹ̀*) Jọ̀wọ́ ọkọ mi,
> Olówó orí mi
> Ọmọ àgbósòkun
> Ọmọ abọ́ba-mọ́-sẹ̀ẹ́
> Ọmọ-a-pa-ná-jàre…
> Jọ̀wọ́ fiyè dénú,
> Ma ṣe ka ẹ̀sẹ̀ yìí sí mi lọ́rùn.
> Mo gbà lónìí pé o fẹ́ràn mi.

(Dòsùnmú 2004:35)

Àkíyèsí tí iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe ni pé ọ̀pọ̀ ìdìlé ni ó ti dàrú, látàri àìní ẹ̀mí ìdáriji àti ìfẹ́. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, ṣẹ̀-mí-ń-bi-ọ́, loògùn ọ̀rẹ́, àti pé òkun kì í hó ruru, ká wà á ruru. Bí àwùjọ bá fi àyè gba ẹ̀mí ìfẹ́ àti ìdáríji, pàápàá nínú ẹbí, a ó rí i pé ìrẹ́pọ̀ àti àlàáfià yóò jọba nínú ilé, nítorí pé ilé la ti í kẹ́ṣọ̀ọ́ ròde.

### 7.2 Fífi Àwàdà Yanjú Ìṣòro Àìnímọ̀ọ̀tótó

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, bí ojú bá ń ṣe ipin, ṣe ni a máa ń yọ ipin, tí à á sì fi han ojú pé ó ń ṣe ọ̀bùn. Ìwà ọ̀bùn Àbẹ̀ní náà ni Àdíjá dọ́gbọ́n fi ṣàwàdà, nípa kíkọ̀ tí ó kọ̀ pé kí Oyèládùn fi àkisà

nu àga fún òun. Ańkásíìfù funfun tí ó yọ jáde tí ó fi nu àgà, tí ó jókòó lé ni ó fi pàrokò ìfòótọ́-ọ̀rọ̀-gúnni-lára fún Àbẹ̀ní pé olóòórùn ni. Àdíjá ni:

> Áà, ó tì o, má fi irú àkísà ìyẹn nù ún… (*Àdíjá yọ ańkásíìfù funfun kan jade ó fi nu àgà náà, ó sì jókòó.*)
>
> (Ìṣọ̀lá 2014:7)

Àdíjá wá ìyanjú sí ìṣòro ìwà ọ̀bùn tí Àbẹ̀ní hù, nípa ṣíṣàfihàn pé ó ṣe dandan kí ilé máa wà ní ìmọ́tótó nígbà gbogbo, kì í ṣe ìgbà tí àlejò bá wọlé, ni a ó ṣẹ̀ṣẹ̀ máa sáré kiri láti tún ilé ṣe. Ọ̀pọ̀ abílékọ ní àwùjọ lónìí ló jẹ́ túbú-ilé, jẹ̀rẹ́ òde, èyí túmọ̀ sí pé ìta nìkan ni irú àwọn ènìyàn bí Àbẹ̀ní ti dára, ilé wọn kò ṣe é rí.

## 7.3 Fífi Àwàdà Yanjú Ìṣòro Ìfojú-Tẹ́ńbẹ́lú Ènìyàn

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Oyèládùn kó ní àǹfààní láti lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ mọ́, nítorí àìrí owó ilé-ẹ̀kọ́ san, síbẹ̀, ìtìjú àwàdà tí Bọ̀sípò fi ṣe mú kí Oyèládùn gbìyànjú láti wá ìyanjú sí ìṣòro iṣẹ́ àṣetiléwá ìmọ̀ ìṣirò náà. Èyí mú kí Bọ̀sípò gbà Oyèládùn ní ọ̀gá. Bọ̀sípò ní:

> O ti gbà á! Oyèládùn, O ti gbà á! Báwo lo ṣe ṣe é?.…Háà! O yà mí lẹ́nu o. Bọ́yá ẹ ti ṣe é ní sùkúù yín tẹ́lẹ̀ ni.
>
> (Ìṣọ̀lá 2014:58)

Àkíyèsí tí iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe ni pé gẹ́gẹ́ bí ètò ìbára-ẹni-gbé-pọ̀, gbogbo ènìyàn àwùjọ ni wọ́n wúlò fún ara wọn ni ọ̀nà kan tàbí òmíràn. Àwọn Yorùbá tilẹ̀ máa ń sọ pé ọmọ burúkú ní ọjọ́ tirẹ̀ àti wi pé gbà fún Gbàdà nílé ni gbà fún Rájí lóko. Kò tọ̀nà rárá kí a máa fi ojú rénà ẹnikẹ́ni, kí ìtẹ̀siwájú lè dé bá àwùjọ wa.

## 7.4 Fífi Àwàdà Yanjú Ìṣòro Ìmẹ́lẹ́ Ṣíṣe

Látí jẹ́ kí Bọ̀sípò ní ìmọ̀lára bí iṣẹ́ ọmọ-ọ̀dọ̀ ṣe rí, Oyèládùn dọ́gbọ́n fi Bọ̀sipò ṣàwàdà, nípa mímú un fọ àwo ní ilé ìdáná, bí ó bá fẹ́ kí òun bá a parí iṣẹ́ àṣetiléwá rẹ̀. Àwo fífọ̀ ṣe àjòjì sí Bọ̀sipò, àmọ́ kò sí ọgbọ́n tí ó fẹ́ẹ́ dá sí i, kí ó má báà gba òdo nínú iṣẹ́ àṣetiléwá rẹ̀. Ó bẹ Oyèládùn pé kí ó má jẹ́ kí òun fọ abọ, ṣùgbọn ìyẹn kò gbà. Oyèládùn ní:

> Ọ̀rọ̀ jọ̀ọ́ kọ́ lèyí. Ó dáa, ìwọ máa fàwo,
> ki èmi máa bá ọ ṣèṣirò.
>
> (Ìṣọ̀lá 2014:59)

Bọ̀sípò gbé ìtìjú tà, ó lọ fọ àwo, Oyèládùn sì bá a ṣe iṣẹ́ ìṣirò rẹ̀. Èyí sì ṣe ìrànlọ́wọ́ ńlá fún Bọ̀sípò láti jẹ́ kí ó mọ iṣẹ́ iléé ṣe.

**8 Agbálogbábọ̀**

Fífi àwàdà yanjú ìṣòro ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ nínú ètò ìdílé ni iṣẹ́ yìí dá lé. Lárá àwọn ìṣòro wọ̀nyí ni a ti rí ìwà àìníteríba fún ọkọ, fífi agbára òkùnkùn ba tọmọnìkejì jẹ́, àgbèrè àti pánṣágà ṣíṣe, lílo ọmọ-ọ̀dọ̀ ní ìlòkúlò, kíkẹ́ ọmọ ní àkẹ́bàjẹ́, ìwà àìnítẹ̀ẹ́lọ́rùn, ojúkòkòrò, àìnísùúrù, àìníforítì, ìwà ahun, nínà owó ní ìná àpà, ìwà àìgbọ́ràn àti oríkunkun, ìwà ìbanilórúkọ jẹ́, ìwà ìpáǹle, irọ́ pípa, ìjà jíjà, àìníṣẹ́ lọ́wọ́ àti àwọn ìpèníjà mìíràn tí ó ń dí àlàáfíà àwùjọ lọ́wọ́. Kì í ṣe pé àwọn ìpèníjà wọ̀nyí kò sí nínú ètò ìdílé ní ìgbà ìwáṣẹ̀, àmọ́ àwùjọ máa ń pe àkíyèsí àwọn oníwà kò-tọ́ sí ìwà ìbàjẹ́ ọwọ́ wọ́n nípa ìlò àwàdà àti àwọn ohun ìdẹ́rìn-ín pani mìíràn tí wọn yóò sì so ewé agbéjẹ́ mọ́wọ́, èyí máa ń mú àyípadà rere bá olùfaragbà ní ọ̀pọ̀ ìgbà tí yóò sì jẹ́ ẹ̀kọ́ ìwà ìkóra-ẹni-ní-ìjánu fún àwọn tí ó kù. Àbájáde iṣẹ́ ìwádìí yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwàdà lè yanjú ìṣòro ìdílé dé àyè kan ní sáà bágbàmu yìí. Iṣẹ́ ìwádìí yìí fi hàn pé àwàdà sì fi ẹ̀ṣẹ̀ rinlẹ̀ bíi ti àtijọ́ nípa pípe àkíyèsí ẹni sí ìwà ìbàjẹ́ tí ó hù nípasẹ̀ ìlò ẹ̀rín rínrín. Bákan náa, iṣẹ́ ìwádìí yìí jẹ́ kí a ní òye pé ìlò àwàdà máa ń ṣiṣẹ́ ìwòsàn fún ọkàn tí ó gbọgbẹ́, tí àlàafíà yóó sì tó àgọ́ ara irú ẹni bẹ́ẹ̀ nipa ẹ̀rín rínrín, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú ìgbeyàwó Èyítáyọ̀ nínú ìwé *Ìyá Yáádì*. Lákòótán, iṣẹ́ ìwádìí yìí rí i pé àwàdà ń jẹ́ iṣẹ́ tí ó yẹ kí ó jẹ́ fũn àwùjọ dé àyè kan nípa ṣiṣe àtúnṣe sí àwọn ìwà ìbàjẹ́ tí ó ń bá ìdílé fínra, tí èyí sì mú àlàáfíà jọba nínú ìdílé.

**9 Àbá àti Ìmọ̀ràn fún Ọjọ́ Ìwájú**

Iṣẹ́ ìwádìí yìí dá a lábàá pé kí àwọn òǹkọ̀wé alátinúdá má kàárẹ̀ nípa kíkọ́ àwọn ìwé ajẹmáwàdà, yálà ìtàn-àròsọ, eré-onítàn tàbí ewì. Nipa ṣíṣe èyí, ẹ̀kọ́ ìwà ìkóra-ẹni-ní-ìjánu àti ìwà ọmọlúàbí yóò lè fẹ̀ṣẹ̀ múlẹ̀ dáadáa, níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé àwòjíji àwùjọ ni iṣẹ́-ọnà alátinúdá jẹ́. Àbá mìíràn ni pé kí àwùjọ yéé máa fi ọwọ́ rọ́ gbogbo àṣà àtijọ́ tí ó ń mú itẹ̀sìwájú bá àwùjọ sẹ́yìn, kí a máa ṣe àmúlò èyí tí ó wúlò níbẹ̀, kí a má jẹ́ kí àṣà ìgbàlódé jẹ gàba lórí àṣà ilẹ̀ wa nítorí pé ọmọ àlè níí fi ọwọ́ òsì júwe ilé bàbá rẹ̀. Kí á gbiyànjú láti máa lo ọgbọ́n ìjìnlẹ̀ tí àwọn baba wa lò ní ìgbà ìwáṣẹ̀, nípasẹ̀ ẹ̀kọ́-ìwà àjèjí-ọwọ́-kan-kò-gbẹ́rù-dórí, tí ayé fi rójú ráyè, tí ìlú sì tùbà-tùṣẹ ní ìgbà tiwọn. Ní àkótán, àbá fún ọjọ́ ìwájú iṣẹ́ ìwádìí yìí ni pé àyè sì wà fún aṣèwádìí mìíràn ní onírúurú ọ̀nà, láti ṣe àyẹ̀wò ṣíwájú síi nípa bí àwàdà ṣe lè mú ìdàgbàsókè bá àwùjọ ju ti àtẹ̀yìnwá

lọ nínú ìdílé, nípa ṣíṣe àyẹ̀wò lórí kókó-ọ̀rọ̀ mìíràn tí ó fara pẹ́ iṣẹ́ yìí nínú àwọn ìwé lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ.

**Àwọn Ìwé Ìtọ́kasí**

A Dictionary of the Yorùbá Language (2008). Ìbàdàn: UPL.

Adébọ̀wálé, O. àti Adélékè, D. (2021). *Àkọ̀tun Èdè Ìperí Yorùbá (New Yoruba Metalanguage) Ẹ̀gbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá.* Graceville Publishers. 1-206.

Adéfowópè, G.0. (2014). *Àfiwéra Kókó-ìtàn, Ìfiwàwẹ̀dá àti Ìlò-èdè nínú Ìwé Eré-Oníṣe Èyí tí Akọ Kọ àti Èyi ti Abo Kọ*. Unpublished *M.A. Desertation* in Department of Nigeria and Foreign Languages; Faculty of Arts, Ọlábísí Ọnàbánjọ University, Àgọ́-Ìwòyè.

Adágbádá, O. (2014). *Ṣé Dandan Ni?* Montem Paperbacks.

Adégbìtẹ́, T. (2019). Nigeria's Comedy Industry-Joking into Billions. https://www.linkedin.ncomlpul.Retrieved in October, 2021, pp 23-25.

Adéjùmọ̀, A. (2001). Ìṣẹ̀fẹ̀ nínú àwọn Ìwé Eré-onítàn Yorùbá. *P.hD Thesis,*Center for Advance Studies of African Society, 1-33.

Adéjùmọ̀, A. (2013). Satire as Protest in an Indigenous Festival: the Case of Ẹ̀fẹ̀. International Journal of Humanities and Social Science Invention: 2(7):43-50.

Adélékè, D. A. (2017). Fágúnwà Current Studies in Yorùbá Culture, Language and Literature. *A Festschrift for Professor Olugboyega Alaba*. Department of Linguistics, African and Asian Studies, Faculty of Arts, University of Lagos, Nigeria, 2-3.

Adélékè, D. A. (2020). The Foolery of Man Beyond the Theatrical World: Perspectives from An Indigenous African Literarary Critic. *An Inaugural Lecture* delivered at the University of Ibàdàn, Ibàdàn, Nigeria, 118-138.

Adéoyè, C. L. (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá.* Oxford University Press Ltd 260-278.

Adéyẹmí, L. (2006). *Tíọri Lítíréṣọ̀ ni Èdè Yorùbá.* Shebiotimo Publications, 8-29.

Àlàbá, I.O. (1916). Fágúnwà gẹ́gẹ́ bí Apaanilẹ́rìn-ín Ònkọ̀wé Alátinúdá. (eds) Adébọ̀wálé, O, Adélékè, D àti Adéjùmọ̀, A. *Ọ̀tun Ìmọ̀ nínú Ìtàn Àròsọ D.O Fágúnwà.* The Capstone Publications, 79-80

Àlàbí, O.S.(2021). An Exploration into the Satiric Significance of Abuse in Selected Nigerian Drama. Alicante Journal of English Studies/Revista Alicantina de Estudios Ingleses, (35): 143-162.

An Essay on Comedy by George Meredith http://www.gutenberg.org>flies 23/1/23.

Bámidélé, L.O. (2000). *Literature and Sociology.* Stirling-Horden Publishers, 16.

Bámidélé, L. O. (2001). *Comedy: Essays and Studies*. Stirling-Horden Publishers, 2.

Bergson, H. (1981). “Form Laughter in Comedy: Meaning and Form”. Rorbert, W. Harper and Row Publishers, 328-332.

Dòsùnmú, B. O. (2004). *Ìyá Yáàdì*. Ìbàdàn: Rasmed Publications Ltd, 1-65.

Heath, M. (2009). *50 Classical Review Comedy*. https://www.Jstar.org>stable.

Hornby, A. S. (2000). *Oxford Advanced Learners' Dictionary of Current English*. Oxford University Press, 112.

Hotwax (2014). “20 Funniest Quotes from Patience Jonathan You've Never Heard” Nairaland/GeneralNairaland.hhps://www.nairaland.com.http://www.boredpanda.com/self-deprecating-jokes.

Ìṣọ̀lá, A. (2008). *Fabú: Akójọpọ̀ Awàda.* DB Martoy Books, 1-124.

Ìṣọ̀lá, A. (2018). *Nítorí Owó*. Osogbo: Sumob Publishers, 1-103.

Mordi, A. O. (2020). Iṣẹ́ Tí à n fi Àwàdà jẹ́ nínú Fiímù Àgbéléwò Yorùbá. *Ọ̀pálábà: LASU Journal of African Studies*, 112-117.

Okafor, S.O. (2015). The Role of Satire in African Literature: A Critical Review of Ugomma, An Igbo Drama by Godson Echebina. *2nd ICLEHI,* 74.

Onyerionwu, E. (2013). Stand up Comedy as a Pop Art, Vanguard News Nigeria. 19 May, 2013.http://www.vanguardngr.com/2010/05/stand-up-comedy-asa-pop-art/.

Oxford Advance Learner's Dictionary (2000). 6th Edition. London: Oxford University Press. 31.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí, A. (2014). *Tíọ́rì àti Ìṣọwọ́lò-Èdè. llé-Ifẹ̀:* Obáfémi Awólówo University Press, 36-37.

Campus, Triban University, Kathmandu, Nepal. Retrived Sept. 2022 From< Raj Kishor, S. (2012). "Humour, Irony and Satire in Literature". International Journal of English and Literature (IJEL). Vol. 3, (4). p. 66-72 TJPRCPVL. Ltd. Sanothimi http://en. Wikipedia.org/wiki/humour.

Sàlámì, E.O. (2019). Ọba kì í Pa Ọ̀kọrin: Àgbéyẹ̀wò Àwọn Ewì Ológundúdú Lórí Ìṣèjọba Orílẹ̀-Èdè Nàìjíríà. *Ifẹ̀ Journal of Languages and Literatures*. 151-153.